ASOJE ORO

Mo gb'ere le ... igbekele ... Olowo Dere ti Olorun ... Oluwa ... ni ... sun.

# ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI LEJO

OWE

... epure ... igba ... igba ni igba ...

Ewure wole ... ju'ru fefe, ... ku sile de ...

VOL. XII No 693. LAGOS. SATURDAY SEPTEMBER 17, - SEPTEMBER 23, 1950. KOBO MEJI (2D)

# Okunrin Kan Pa Iyawo Re Nitori Agbere Sise

ABEOKUTA. Oran ko dun nigbati ariwo ta gee wipe okunrin agbe kan ti a npe James Odeufa ti o ngbe abule Oka, ni agbegbe Egba-Obafemi Poko Abeokuta pa iyawo re.

Nigbati o nbu pere-pere nipa ohun ti o fi sababi ki o to pa iyawo re na, olu-ju adajo ninu kotu, keke pa kere, ko di, igba meji ko lu ara won. Omo mefa ni obinrin ti awon pa yi ti bi fun odaran apania yi, oyun si mbe ninu re.

Odaran na so wipe, ohun ti o fa sababi ki on to pa iyawo on na ni pe, agbere sise re poju, gbogbo awon aladugbo lo si mba a lopo.

Ohun ti o mu odaran na lati so oro yi jade ni wipe adajo bere bi o ba ni oro lati so si esun apania ti awon ka mo lese yi.

O so fun adajo pe iyawo on ti nhu irufe iwa bayi lojo pipe ti on si ti nse ikilo fun ti ko gbo, nigba-gbogbo lo ma nwo ile awon aladugbo lo, ti on si fi oju ri, tobe ti o fi so on di ysa si awon aladugbo on.

## GOMINA ATIJO MBO

A gbo pe Gomina Agba ile Nigeria atijo, Sir John Macpherson ti wọko ilu Oyinbo o mbo wa ba wa yo ayo Ominira wa ti ile Nigeria nilu Eko.

**ARA-O-LIN - IPARA ATATA**




ARA-O-LIN je ipara ti a ... O ... gbogbo irufe egbogi ... ti o ba ... O ... ara-lalanlalan, ... ati ... Nkan ... Yoruba npe e ni "ATA". Iwe npe e ni "OCE" Hausa si npe e ni "...". Owo ... 1s. 6d. (9d) ...

The Egba Trading Aradan Stores,
18 Denton Bridge St., P. O. Box 1, Ebute-Metta.

## Ogongo Baba Eiye



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Oloye Dokita Nnamdi Azikiwe ti nse Baba egbe Igbimo nla ni Ijoba Apapo ile Nigeria. On ni Alayelowa Oba ... ilu Oyinbo Ojisi fi ase si wipe ki o ko joye Gomina agba fun ilu Nigeria lehin ti Oloye Sir James Robertson ba fi aye na sile ni ojo kedogun osu November, 1960.

Opolopo iwe iroyin ni o ro'yin si owo Dokita Azikiwe nitori ohun ti o wa ... nilu Rome sile ... o ti ... idaraya agbaye (Olympic).

## Odaran Bu Si Ekun Ni Kotu

EKO. Awon ... wipe ... ni Fetuga, ... si adajo, ... adajo ... ki o lo gbawa ...

Nigbati adajo sa kento na mo Ogbeni Fetuga lara, nse lo bu si ekun gbaragada niwaju adajo ti enikeni ko si le so kini ohun ti o pa a lekun.

Adajo so wipe, eje na ga, sugbon ohun ti o ye ki enikeni mo ni wipe Orisa akunlebo ni Kotu ti enikeni nilati bowo fun. Nibi ni ori Ogbeni Fetuga ba wu ti o si bu si ekun gbaragada.

## INA NLA SELE NI IDI ARABA

EKO - Ile nla oniyebiye kan ti Ogbeni olowo kan fi Buloku ko si Idi-Araba lona Mushin, eyiti awon si laipe yi pelu inawo gidigbo-yan ni ina ti le lori ni de de agogo meta oru ni ojo Alamisi, k'awi-k'afo, ile na jona kan'le.

Awon Panapana Ebute Metta ni ile tete de ibe sugbon ki apa to ka ina na, o ti se jamba Ogbeni kan ti gbogbo enia mo adape oruko re gegebi "Koni ohun ti ko ni opin" ti Opopo Musa Giruba Po ni ile na.

Awon ti le so ohun ti o fa sababi ina na.

## AWON EBI SOMEFUN DA EGBE ISOKAN SILE

ABEOKUTA. Awon omolebi ti Somefun-Okunjindo da egbe ise kan sile ... ile Baba nla won ni agbole Somefun ni Ago Igbein lati ma ba ara won ni ajumose papo ninu ohunkohun. Oloye A.A. Somefun ti ise Bal gun Egba ti o si tun je Olori ebi, lo se alaga ipade ... na. Iyalode Afowape Somefun ti o dagba julo ninu ebi, eniti ... re ti to adorin si opo enia si npe ni "Iya Egbe, lo fi adura si ipade na.

Die ninu awon enia ti aye wa lati darapo won ni Ogbeni J.A.O. Somefun L. Olaoye, Thomlyo, Ladipo, Iyalode Bolaji, Durodola, Babajoko ati Sobedatu ati opo awon enia lati Eko, Ibadan, Ijebu ati lati ile Ghana.

# Electricity Corporation Of Nigeria

## PRESS RELEASE

The Corporation is taking this opportunity to refute the suggestion which appears to have been given some publicity, that plant availability will be inadequate to meet the additional demand over the period of the Independence Celebrations, due to the heavy additional load resulting from the extensive illuminations.

For the information of the public the present Maximum Demand on the Lagos Power Stations is approximately 34,000 KW and this is expected to increase to a little over 40,000 KW as a result of the celebrations. The present available plant amounts to 70,000 KW which is nearly double that required to meet this increased demand.

The public are also advised that local interruptions to the electricity supply during the last few months have been due to extensive road works in progress in various parts of Lagos which have damaged the Corporation's cables and given rise to many faults. These interruptions to the supply, which are through no fault of the Corporation, may continue for some time to come.

**G. E. Wyatt**
Chief Executive Officer & General Manager

## Mogbon - mogbon Mogbon- mogbon Ati Mogbon-jorisa

(Lati ọwọ Ẹgọ)

Baba kan bi ọmọ mẹta, nigbati awọn ọmọ na dagba ti awọn di ọkunrin baba wọn pe wọn mọra o bere pe oruko wo ni ẹgbọn fẹ lati mọje? O dahun pe, ki ẹ ma pe ọni ni Mogbon-mogbon, ekeji ni on yio je Mogbon-mogbon, eketa ni on yio ma je Mogbon-jorisa. Baba wọn tun bere pe tani kọ wipe boni ki o maje?

Ni ọjọ kan Baba won fi a nkan kan fun Mogbon-mogbon ati fun Mogbon-mogbon ekeji kan kan, o wa fun Mogbon-jorisa ni ọna ọgọ, o si ni baba di ọkan ọdun mẹta ti awọn mọ ọmọ mẹji mẹji wa.

Nigbati o di opin ọdun mẹta Mogbon-mogbon mu ọmọ ẹran meji wa. Mogbon mogbon mu meji wa. Nigbati Mogbon jorisa mbo o ra ẹru igi kan ni o fi ri baba rẹ, o ru ẹru igi silẹ niwaju baba rẹ o dimọ, o wipe, heee baba, o ma ku ewu lana ni mo gbọ wipe ẹ bimọ, e pele o ako ni tabi abo?

Baba rẹ dahun pe oro tire yi ma yani lenu. Iwọ ha ti ri okunrin ti o bimo ri? Mogbon jorisa wipe ase iwo mo ohun ti o to ika ni Iwo nse nigbati o mọ pe okunrin ko le bimo nse ti iwo fi fun mi ni eran agbo ti o wipe ki omo-omo re wa?

Oro ti baba re na o wa loro ti pe amode yi fe gbon ju on lo bi on ko ba si tete yanju re yio pa on dano. Kosi pari. An ma gbe aswaju hi baba na fun ran Mogbon jorisa lo sile Ilu ti o si ma ilu o de l'okun o si gbe wa fun baba re.

## Alikali Pase Wiwa Enia Kuro Nilu

LIKORO. Ọkunrin kan ti o nje Mito Maroki, ti nse asiwaju kan ninu ẹgbẹ N. E. P. U., ni Alkali Kotu Zaria dajọ fun wipe iwa rẹ ko dara ni ilu ni torina, ki o jade kuro ni ilẹ Hausa.

Sugbọn ọkunrin na ni ejọ ti awọn da fun on ko tẹ on lọrun, nigbati on ko fọ de, ti on ko si jale, kini ohun ti o le fa a ti awọn fi ni lati ma on jade kuro ni ilu ti a gbe bi, on si lati iwọn ogoji ọdun ti on ti ngbe ibẹ kuro.

Nigbati ejọ na de iwaju adajọ ijọba ilẹ Hausa, o bere pe kini ẹsẹ ọkunrin na, Alatako rẹ sọ wipe, nitori ko ni ilu kan pataki nibiti o ngbe, iwakiwa lo si nhu kakiri awọn abule, ko si ni ise kan lọwọ ti o nse.

Adajọ na sọ pe, ori yi to to nkan ti a le titori re wa ente kolo ni ilu ti a gbe bi. Nitorina, o fa ejọ na ya, ori ki ijọba ibile Zaria lọ san ponun mewa owo itanse fun Mito Maroki.

## ẸJỌ AWỌN TI O PA EGUNGUN BAMGBOṢE

EKO. Awọn ti awọn se omote titi, ti awọn fi la pa Egungun Bamgboṣe si ikorita meta ninu ago si ariin odeỌ ni Opẹpọ Oshodi, awọn ọniti olopa mbo se ejọ apania ni kotu Ọdarun (Assizes) oruko won ni Sọrita Ọlagunju ekeji ni Taoridi Olasunkanmi wipe awọn lo pa Mofadaunu ti o gbe ago egungun Bamgboṣe wo.

Agbẹjọro (Lawyer) ti o wa fun Taoridi Lasunkanmi so fun Adajọ John Bennett ti o nse iwadi lori ejọ na wipe, koi si eri ti o muro to, ti Taorid le jebi lori rẹ.

(Wo yoku loju ewe kejọ)

## Apoti Onifalowo Titun To Sese De



Ọmọbinrin rederedo ti a nwo ninu aworan yi nfi apoti onifalowo kan han wa, esiti mọọ fi ike ṣe, o si nfi olu (Hammer) lu u lati fi han wipe apoti ti o dara ni kole fọ.

# Asiko Ovaltine!

Pẹlu ilera ọkan ati ilera ara, ọmọde ndagba di okunrin. awọn obi ti o gbọn a ma a fun awọn ọmọ wọn ni Ovaltine mu. O ni okun ilera rẹ pataki bọ opolo Ori, awọn iṣan ati ara a si ma a fun agbara ati okun-inu ni agbara kikun. Ebun eda ate-lẹse ti o darajulọ pẹlu ohun ti o nfun ara okun mu ki Oval-tine je ohun mimu ti o dara fun ọdọ ati agba bakanna!




O nfun awọn ọmọde ni imularada pẹlu ilera.


## Baoku Ise O Tan

Okunrin kan wa nilu Eko ti oruko rẹ njẹ Suberu, ekurọ lo nra lọja Ejinrin, o ni awọn Ijẹbu ni Onibara pupọ. On ni awọn Ijẹbu npe ni Suberu "Aladidun ọbẹ", Itumọ eyi ni Suberu ọlọbedidun.

Ko si ọalti o le fi ọwọ r Suberu ṣẹh'n nibi ekurọ ati epo rira. Bi Ijẹbu kan bati nra ekurọ tabi epo bọwa, awọn o sọ pe ọdọ Suberu ni awọn nlọ, a ma ra ekurọ to kun ọkọ kan o si nra garawa epo rẹpẹtẹ.

Suberu lo jẹ oye Giwa fun awọn ẹgbẹ rẹ, bi o ba di ni ọjọ Sunday, gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ yio ma ho yanmu ti awọn o ma jẹ ti awọn o si ma mu.

Nibikibi ti oniluọ rẹ ba pade rẹ yio ma fi ilu sọ bayi pe:

Suberu, Suberu,
Enia ko m'oni,
Ọlọrun mọ ọla,

ni akoko na ni Suberu nnawo bi ẹlẹda, nibikọsi ti o ba ba awọn ẹgbẹ rẹ lọ, lo ngba iyi, olowo ni gbogbo enia mọ Suberu si, iyawo mẹfa loni, bayi ni aiye nyẹ Suberu, ko si ẹgbẹ kan ti o le fi ọwọ rọ awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ ti.

Nigbati o ṣe, lọdun kan ti nwọn fi owo kun owo ekuro ati epo, ọkọ epo mẹta ati ọkọ ekurọ mẹrin ni Suberu ra. Ṣugbọn nigbati gbogbo ọkọ awọn de Langbasa, gbogbo ọkọ epo ati eko e urọ ṣe ṣ ra sian ọna.

(Wo yoku ni oju ewe kẹfa)

# ELETI - OFE

ANJUWON KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
Kosoko Street, Lagos. "ELETI — OFE, LAGOS
P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. XII. NO. 693. SATURDAY SEPT. 17, — SEPT. 23 1960


## OMOLUWABI

—O—

Lori ọrọ iyanju ati imọran atata ti Alabojuto iṣẹ ati alafia ilu, Ọgbẹni J. M. Johnson (Minister of Labour and Welfare) gba wa gẹgẹbi ọmọ ilẹ Nigeria, lori ero asọrọ-magbesi, nipa iṣẹ wa ati ihuwasi wa ti a nilati ṣe itọju rẹ ni asiko ominira ilẹ wa, ki a le jẹ oruko ti a fi ṣe akọle oke wosika wa ọsẹ yi, loju awọn ọpọ ijinmi ajeji enia, pataki pataki ti yio wa ba wa yọ ayọ isọdominira ilẹ Nigeria wa lọjọ kinni oṣu October, 1960.

Imọran na kan fun ọgbọn ati laakaye, ki a ṣe agbara lati fi ṣe iṣẹ ṣe gẹgẹbi imọran rẹ na. Ekini: Ki a ni iwa ọyaya ati ife si awọn alejo ti o ba ba wa ṣe alabapade ni ayẹyẹ, nipa ṣiṣe iranlọwọ fun wọn gẹgẹbi o ti tọ ati bi o ti yẹ. Ekeji: Ki a maṣe jẹ awo'ni maṣẹfo, nipa wiwo awọn ajeji enia na ni awodiro, iwa ibuku ni eyi jẹ. Ẹkẹta: Ki a fi ohun ọṣọ ilẹ wa han nigbagbogbo asiko ti ao fi yọ ayọ ominira wa na, nipa aṣọ ilẹ wa ni lilo dipo ti ilẹ ajeji ti a nkaṣa rẹ, ati pe ki awọn obinrin ọlẹyinju-ẹgẹ ilẹ wa di irun ori wọn gẹgẹbi aṣa ilẹ wa, ki awọn maṣe ko irun ori wọn ni alarabara, eyiti ko nṣe aṣa ilẹ wa nitoripe, iran iṣẹ wa, ihuwasi wa ati gẹgẹbi a ti nlo ni ilẹ wa ni ohun pataki ti awọn ajeji enia na wa wo.

Bi a ba le tẹle imọran wọnyi, nigbana ni a o jẹ "Ọmọluwabi" ti awọn alejo wa na ko ni le yọ ṣuti ete si wa nigbati nwọn ba pada de ilu wọn.

Imọran ti o dara ni, ẹ jẹki a tẹle.

## ENITI ONTA OTI ROBIROBI FI PONUN MEJO GBADI

ABEOKUTA. Ọkunrin kan ti o nje Lawani Akibode, ẹbẹẹgba ọlọpa odan lori ni awọn olopa nmu fun ẹrun wipe nwon ri oti robi-robi tabi ti a nwon npe ni Oyinbogo lowo rẹ.

(Wo yoku loju ewe karun)

## Ye Owo Re Wo

(Lati owo Q.ogbon)

Yẹ owo rẹ otun tabi ti osi wo, iwo yio ri awon ila ti o leda ko sibe, awon ila wowe po bi omi, ṣugbọn meta tabi merin ni awon ti o je nlanla. Lori awon ila nla awonyi ni ao soro die le lori.

Ekini ni ila okun emi ọn lo bere lati palaka ika Atanpatako owo ati ika ifabela, lati ibe, o yi roboto lo si orun owo.

Ekeji tun bere lati okun emi ti bere, o si la arin owo la titi o fi de arin meji owo ti o si duro eyi ni ila ogbon ori Eketa bere lati egbe owo titi lo si arin meji ika ifabela ati ika ti o gun julo eyi ni ila agbara imo. Bi ekerin ba wa eyi ni ila Arisiki, a ma bere lati orun owo titi lo si isale ika to gun julo.

A o koko soro lori ila arisiki yi Ẹnikeni ti o ba ni ila asiki yi ni owo re nilati ni owo lowo. Bi ila arisiki ba nipon ju ti emi lo, oluwa re yio feran owo ju emi re lo, ko si ko lati fi gbogbo agbara re wa owo lonakona ti o ba ri.

Bi ila tere kan ba lo da ila arisiki yi koja bi oluwa re ba ti nri owo na nina ajadi apo ni yio ma ko si.

Iyawo oluwa re yio ma fi igbagbogbo ro ejo oko kiri pe ko fun on ni owo, awon obi eni na yio ma fi oni rojo omo won fi ola rolo, gbogbo iwa omo na ko ni je eyiti o dun mo won ninu.

Oluware yio si ma fi igba gbogbo rolo aini lenu ise. Bi ila arisiki yi ba lemo okun emi, itumo eyi nipe, iya oluware ni yio to sugbon bi ko ba fi ara mo baba ni yio to eni na.

Awọn to ni ila arin yi lọwọ bi ohun baburu kan ba de si wọn lọnu iṣẹ edekoyede yio de sarin on pelu iyawo rẹ ati awọn obi rẹ pọlu lasiko kanna.

## Awolowo T'ajo De



Nigbati Oloye Awolowo pada de sile lati ilu Rome, o da obi fun ijoba wipe ko si iranlowo to lati odo won ni ko jeki awon Oṣere wa le yege ninu ere won; ko si npe ejo awon omo ti nwon ṣe alaimura to.

Bi o ba je wipe iranlowo to won ni, iṣe won iba san die.

## ODE KAN KU SIGBO ERIN

ONITSHA—A gbọ irohin wipe ọkunrin ọdẹ kan ti nwọn npe ni Igbasogo ara ilu Anambra, ma fi igba gbogbo ṣe ọdẹ lọ sinu aginju igbẹ leti odo Anambra, a si ma pa awọn akẹran wa sile.

Ṣugbọn lọjọ buruku ki ẹṣu gba omi mu, ọkunrin ọdẹ na lọ ni ero lati rin jinna sinu igbẹ tobẹ, nitorina ko gbe ibọn Oyinbo dani, ibọn Ṣakabula lo gbe dani, ero rẹ ni lati wa igboje die.

(Wo yoku loju ewe karun)

# Olopa Ile Nigeria Nko Fere Alabapo Nilu Oyinbo



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Sajl ( Sergeant ) James Egege ti işe olian ninu awọn Ọlọpa ilẹ Nigeria, ti o lọ kọ işẹ nilu Oyinbo.

A gbọ wipe, o ti kọkọ lọ kọ işẹ nilu Scotland, ibẹ lo wa ti o si nkọ fere alabapo ti a nwo lowo rẹ yi.

Eniti a nwo yi ni yio fọn fere alabapo fun Ọmọba Alexandra ni akoko ayo Ominira ilẹ Nigeria ninu oşu October.

## Eniti O Nta Oti Robirobi

( O bẹrẹ lo'u ewe kẹrin )

A gbo wipe Lawani gbe Garawa o t i k a n dani larin ojo Şapọn, ibẹ ni awon ọlọpa t i kofiri rẹ ti nwon si famu.

Nigbati awon ọlopa idiwọn gbogbo oti ti nwon ri gba lowo okunrin na, o to iwon galonu mẹrin ati igo meji. Adajọ ni ki Lawani lọ san Ponun mẹjọ, bi ko ba si ri san, ki o lo si ẹwọn oşu kan.

## Ijagboro Be Sile Ni Agbegbe Ile Benue

BENUE, Ijagboro kan bẹ silẹ leti odo Binuwẹ ti o di ohun ti awọn ọlọpa ni lati da si, enia mọkandilọdunrun ni ọwọ tẹ ninu awọn enija na.

Fun odidi ọjọ meji gbako ni awọn enia na fi dana sun ile ara won. A tilẹ gbọ pe awọn awọn enia mẹkandilọgbọn kan ninu awọn enia na, nigbati nwon gbọ pe awọn ọlọpa mbọ, nwọn lọ ba ni buba, nitori ki nwọn le ko awon ọlọpa na ni ẹiye ko sọka.

Gbogbo ete ati ero wọn ni awọn ọlọpa ti mọ. Igba enia ti nwọn lọ lumọ si kọkọ lati ba se won ni jamba, gbogbo won ni ọlopa ko ni igbekun.

Ni alaijẹ pe awon olopa yinbon si awon enia, sibẹ, Ọlopa şẹgun won. Gbokegbodo ti Ijagboro na da silẹ mu ki agbara Ijoba ibilẹ T I V rolẹ tobẹ, opọlọpọ agbara Ijoba Nigeria lo jẹki gbogbo rogbodiyan na rolẹ patapata.

## Ijo Methodist Ilu Owo Di Ominira

ỌWỌ. Irohin ta si wa leti wipe lati ibẹrẹ oşu September 1960 ni awon Ijo Methodist tilu Ọwọ Ifaki, ati ti Aiyedun di Ominira ti a w o n si gba aşẹ lati ma mojuto nkan ara won funra won.

Latigbana wa, ni awọn Ijo nwonyi ti bẹrẹ si şe ipalẹmọ ẹlẹrẹbọ ti nwon o fi yo ayo ominira won.

( Wo yoku loju ewe keje )

## ỌDẸ KAN KU SI IGBO RRIN

(O bẹrẹ loju ewe kẹrin)

Gẹrẹ ti o wọ inu igbẹ na lọ, pẹkiraki lo se pelu akọ-erin, lo fa yin ibọn Şakabula owo rẹ ba erin na ni owo ija rẹ A gbo pe nigbati erin gbọgbẹ o bẹrẹ si le ọdẹ na titi o fi ba a o fi owo ija rẹ mu ni agbede meji, o si fi ori rẹ san igi titi ọde na fi ku.

## TIAMIYU ŞOMEFUN SỌ ỌMỌ RẸ NI ORUKỌ

ABẸOKUTA. Ọgbẹni Tiamiyu Kọlawọle Şomẹfun, ati Safuratu Alaki iyawo rẹ lo fi ile pọn ọti, ti awọn si fi ọna rok^a nigbati awọn nşe isọmọ loruko. Ara, orẹ ati ẹbi gbogbo lo peju pẹsẹ si agbole Şomẹfun ni ile rẹ ti o mbẹ ni Igbein.

Oruko ti awon fun omo na niyi Awanatu Adetowun Iyabode Alufa Asani Ayikondu lo kewu ti o si fi oruko omo na han, ọpọ awon Alufa wa nibẹ pẹlu.

Awon ẹgbẹ Aiye Idẹra tabi Aiye Alafia, ti iyu tunfulu na jẹ Olori fun wa ni bi ase ejo na, bẹni awon ẹgbẹ Ifẹlodun si dabira nibẹ pẹlu.

Diẹ ninu awon gbajumo ti o wa si bi isomo l'oruko na ni Oloye A. A. Somẹfun ti işe Balogun Ẹgba, Igbimo S. O. Ewebiyi, Sanusi Adegboyega ti işe Balogun ẹgbẹ Aiye Idẹra Iyafin Salamotu Baruwa Safuratu Lika ati ọpọ enia lati Eko Ijebu Gbana ati awon ilu okere miran.

HINDU SANKARA'S

Religious Art Jewelleries



HINDU SANKARA, 30 ... Row,
Blackheath, London, S.E.3, England

## ỌMỌ KO LAYỌLE, ẸNI ỌMỌ SIN LO BIMỌ

ABẸOKUTA. Gbuke ni a gbọ irohin iku Iyafin Saidatu Adewumi Ọdunlami ti agbole Arilegun-Jeru, on si ni iya ti o bi Ọgbẹni I. L. Braimọ ti iṣe R'pọtọ (Inspector) fun awọn ọlọpa ibilẹ. Iya na ku fi aye silẹ nigbati o di ẹni ọdun marundiladọrin (85 years).

Awọn eto ti awọn wa sibi oku iya na le ni ẹgbẹrun. Diẹ ninu awọn eeia pataki ti o wa sibi oku iyagba na ni Lemomu Oke Ọna, Alufa Durowoju ni o ṣe isin isiku iya oninure na, awọn Alufa Shittu Arowasi ati awọn Imale pataki pataki ni o ṣe isọngbe rẹ.

Ẹgbẹ Nawairu - Deen ti Ọgbẹni I.L. Buraimọ, jẹ Ọpẹmaiero ẹgbẹ na ṣe Fidau nibi oku iya na lẹhin ti awọn alufa ti kirun ni Jara tan. Oruko awọn ọmọ oloku niwonyi; Asana Buraimọ, Oseni Buraimọ ati Suberu Buraimọ.

Awọn eeia pataki ti o wa sibi oku na ni Ọlọye V.A II ti M.B.E Alhaji, A.W Lemboye, Y.M. Abudu, T.S Calfos, T.A Fajeb., Idris Bello K.A.G. Adetọna, Willie Shosan, O. Akinsanmi S.O Salami Alhaji Salami, Modiyu ti iṣe Lemomu Ilaro A.W Amode Jimo Musa Hodja Nimota Ilaro ati Ọgbẹni S.B Tella lati Ilaro ati ọpọ awọn eeia

Ki Ọlọrun fori jin iya.

## Efufu Lile Ja Ni Ijebu-Ode

IJẸBU—ODE A gbọ irohin wipe ọjọ ẹta kan rọ eyiti o fi afẹfẹ lile siwaju ni ilu kan ti awọn npe ni Oloworo ni agbegbe Ijẹbu-Ode ẹfufu na le tobẹ ge ti o fi wo ile ijọsin ti Ijọ Aguda lule.

Ẹfufu na le tobẹ lojo ọna Mọto ti o lọ lati Ijebu Ode si Ejinrin ti o ba fa igi ya lati ina igbẹ lojo ọna ni ... u bọwa gbogbo awọn mọto ti o nlọ si oja Ejinrin ni lati ya si ẹgbẹ kan, fun iwọn wakati mefa

Ko dai ewu nla lo kọja lori Ọgbẹni W. O. Erinle ti iṣe akọwe igbimọ (Secretary Treasurer) nigbati ẹfufu yi ya eka igi lati inu igbo, ti o si fi bo mọto rẹ mọlẹ pira loju ọna ilu Kete-Oke nitosi Oja Ejinrin.

Akowe igbimo na ko fi ara ṣeṣe, ṣugbọn a gbọ wipe mọto rẹ baje. Bi o tilẹ jẹ wipe ko si ẹmi ti o ṣofo dano, sibẹ ọpọ dukia lo baje awọn ohun ọgbin pupọ lo si baje ninu oko.

## Baoku Ise O Tan

(O bẹrẹ loju ewe kẹta)

Latigbayi ni ibanujẹ ti gori ẹmi Suberu, o fa a lọtun fa a losi, sibẹ koto ara wọn mọ. Suberu bere si ta gbogbo dukia rẹ, aṣọ rẹ ati awọn ile ti o ni, sibẹ ko kaju gbese, aṣẹhinwa asehinbo, Suberu di ẹdun arinlẹ.

Ko le lọ si ọja mọ, ile ọdọ aburo rẹ lo tun npada wa gbe. Ko ni gẹ, ko ni go, Suberu Alusidun ọbẹ tun pada di Suberu eleweto.

Koni pari, ao ma ba nlọ lọse ti o mbọ.

## Bi Ako Ba Pa Iji Han Iji Eru Koni Ba Iji

Lọjọ kanna ni Adoko ma-bẹrẹ fẹ dan Orunmila wo ko si ti igbọ pe ohun kan sele si Abẹrẹ-tile lọsi oko. Bi o ti gbe ọpẹlẹ rẹ ti o jan mọlẹ, fasa ni Ọrunmila tun yọ si, o bere wipe Ifa kini ey ti o da loni ? Ọmọ awo na si da hun wipe Otura Orikọ ni. Bi o ti wi nayi tan, ọrun rẹ yi si ẹhin, o ku.

Ọrunmila ni Ajọwo.
Mo ni Ajọwo
Ohun ti a ba jọ wo
Lo ngun regerege,
A da Ifa fun.
Aroguro-toko-wale,
Lọjọ ti o sọpọa poro
Lẹhin Orunmila,
O ni mojewọ ope
Ki o daṣẹ bomi,
Otura meji.

Ọrunmila gberaṣo di ile ọmọ Awo kẹta bi o ti de ile Aroguro tokowa-sile o ba ni bi ti o gbe lan ọpẹlẹ rẹ mọlẹ Ọrunmila yọ si o ni Ifa ki-i eyiti o da loni ? Bi o ti ri pe Oluwa on ni o yara gbe ọpọn Ifa rẹ soke o wipe ẹ ma bami wo o nko ma mọ.

Nigbana ni Orunmila wa ki Ifa rẹ bi a ti kọ si oke yi. Ifa yi kọ wa pe, ko dara lati ma ṣe moto moto si ọga ẹni. O pari.

## AWON ARA ILE SCOTLAND YE ARA NIGERIA SI



Iboye ti a nwo ni awọn ti o fi awọn gbalaja korua ninu aworan yi ni Sir Ian Johnson Gilbert ti iṣe Lord Provost of Edinburgh, on ni ẹniti o gba awọn ... mọ Akekọ ti o wa lati ile Nigeria lọlẹ. Oruko wọn ninuwoyi:-
Ọgbẹni L. F. Fagbola, Iyafin Abimbola Osafẹwọkan, P. I. Okwawa lo fi jigin soja, ati Oloye J. L. Omoworare.

**Kere o!**

Ati ni oriṣiriṣi egbogi fun arun Inarun ati arun Jẹdijẹdi, (Bitter Tonic Liquid of Life) Tete wa ra tirẹ, t'ọkunrin ati t'obinrin ki o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORE
7, Egerton Road, Lagos.


Mmm.mm..m...m.... the
orange drink with the big Green M
Mirinda
TRADE MARK
Mirinda brings "Good Life" to them,
the orange drink with the big green "M"
Mmm...mm...m...m...m...
Mirinda
BOTTLED UNDER THE AUTHORITY OF THE PEPSI-COLA COMPANY OF NEW YORK BY
"WNDC - PEPSI COLA PROJECT"

# Nigerian Ports Authority

## PUBLIC NOTICE

### INDEPENDENCE CELEBRATIONS CLOSURE OF PORTS

It is hereby notified for general information that the following ports will be closed on the dates shewn opposite them and that no port operations will take place at such ports on such dates:-

| PORT | TO BE CLOSED ON |
|---|---|
| Lagos | — 1st and 2nd October, 1960. |
| Port Harcourt | — 1st, 2nd and 10th October 1960. |
| Other Ports | — 1st and 2nd October, 1960. |

**Bayo Kehinde**
Secretary to the Authority.

N.P.A. Notice NO. 468
30th August, 1960.

## EJO AWON TI O PA EGUNGUN BANGBOSE

( O bere lojo ewe keji )

Suchon awon ti wipe awon ti Teoridi ni gba ti o nle egungun Bangbose lo. Agbejoro na so pe eri yi nikan ko to ohun ti enia le fi gba wipe on lo pa egungun na. Adajo Bennett papa gba wipe iru eri yi ko to ohun ti enia fi le mo kini ohun ti o fe se nigbati o sare tele egungun na lehin.

Alatako tun nau adajo leti wipe, ni abe bodi ni olopa ti lo mu Teoridi bi ko ba ni ohun ti o ti se kini ohun ti o le gbe de abe bodi. Adajo ni ki Teoridi ma lo ni alafia. O wa ku Shitta Olagunju nikan sogo leno re. Koko pari o di ose ti o mbo.

## EDEGBETA ENIA DI ALAINILE LORI NILE TIV

GBOKO. A gbo irohin wipe awon ti nwon fi ina kun de won sile awon Damagudu (Tiv) to iwon edegbeta enia ti awon di alainilegbe. Ijoba ibile Damagudu fun awon enia na ni aso Balankiti kokan, o si ba won wa ile ti nwon o ma gbe nitori akoko otutu ni ewa yi.

Nitori ero a te ina bole a ko te ina bole yi, a gbo wipe ogulogo awon enia ti o wa ra abuleko kaladi ti ko eru won, awon si kori si igboro ilu nitori ki awon ti o nfi ina kun ile ma ba te ina bo ile won ni oruganjo nigbati nwon ba ti sun tan.

Lojo Monday ose tokoja, iwon igba enia ninu awon Fulani ti o nda malu kiri, ti awon fi ina kun ile won di alainitiki ninu Damagudu pelu awon omo won, aya won, iya ati arugbo won ti nwon nwa ibiti won o wo si nitori otutu.

## Oku Olomo Gege Lao Gbe

ABEOKUTA. Irohin ko to afojebe niti eto isinku Baba agba ti oruko re nje Daddy Solomon Bankole, eniti o ku fi ile aiye sile nigba ti o di ẹni odun mọkandilọdọfa (109 years) ninu ile re ni Ago Egun Street ("Bankole House") ni Igbein.

Ologbe Daddy Solomon Bankole yi l'eniti o koko te Abule Bankole di ni agbegbe Egba-Obafemi. Nibi Abule [illegible] lo gbe wa titi o fi [illegible] so. On kanna ni Baba [illegible] Anglican Church ti abule Bankole.

Nwon gbe oku re lo si ile Saint Paul ni Igbore, nibe ni se isin ikehin fun oloogbe. Awon omo oloku po jantirere ti gbogbo nwon nko orin bayi wipe:-

Ile o, ile o,
Baba rele o,
Ile l'o lo tarara.

Awon omo ti oku na bi ati awon omo-omo ti a le daruko nibayi, Isaiah Bankole, Emmanuel Bankole, Yemi Bankole, Alas Bankole, Emily Bankole, Fo'orunso Bankole, Fola Bankole

Ehin baba na yio dara




Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company 28, Kosoko Street P. O. Box 457 Lagos Phone. 233